**For Sale**

3, Toner Bedford Lorry (Bolẹkaja) with all Particulars correct Available for inspection, at 37 Ojuelegba Road, Suru lere.

Phone, 12, Suru lere Or 21985, Lagos.

c

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

Ọja Gbanjo

Tete wa ra stẹ ki o tolan Kerosine Stove titun to sẹsẹ de. Iye owo rẹ telẹtẹlẹ 35/-

Iye owo nisisiyi 30/-

Bere ni

ANJỌRIN Bros & Co
118, Griffith St, E. B.

Y. AROWOLO
The Manager

VOL. III No. 123 MONDAY NOVEMBER 9 — NOVEMBER 15 1959 KỌBỌ KAN (1d)

# Ile Naijiria yio di ilu ti a ngbon EPO ninu re

Ogbeni R. P. R. Mcglashan ti o jẹ Alaga awọn Oyinbo Shell sọ wipe, nigbati o ba se, ile Naijiria yio di ilu ibiti a ti ngbon Epo moto nitori refelu.

Oyinbo na sọ wipe, bi o ba jẹ wipe ṣẹ wọn n r i n lọ gere ninu epo ti awọn nwa yi wọn fẹ gbe e n u ija ti o wa ni okun Bonny ko awọn ọkọ nlanla le ri aye gba wọ inu ọsa.

Bi ọrọ na ba juṣe bẹ, ilẹ Naijiria yio ma gbon agba epo bi iwọn 30,000 lọ silu Oyinbo ni ojojumọ, ati ni gbati yio ba fi ma lọ si opin ọdun 1960, ilẹ Naijiria yio ma gbọn to iwọn 40,000 agba epo n i o j u m ọ kan.

Ni ọdun 1958, iye agba epo ti a nri gbọn nigbani lojojumọ jẹ 7,000, lọdun ti a wa yi, ni a ngbọn i y e 15,000 iye agba epo.

Bi o ba di lọdun 1960, iye owo ti awọn yio s a n fun Ijọba ilẹ Naijiria jẹ £750,000

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹrilọ lẹyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pẹlu Enjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Mato.

O WA NI SỌBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun Street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## Satide ni ojo isinmi Seventh day

ABA. OLUKULUKU AWỌN IJỌ ONIWASU LO NI OFIN TI NWỌN NTẸLE. BI IJỌ C.M.S., R.C.M., METHODIST, AFRIKA, S.I.M., SALVATION ARMY SEVENTH DAY ADVENTIST, ATI BẸBẸ.

Igbagbọ ijọ Saturday Sunday (Seventh day) ni wipe gẹgẹbi a ti ka ninu Bibeli pe, Ọlọrun pari iṣẹ rẹ n i ọjọ mẹfa, o si simi ni ọjọ keje. Ọjọ keje na si jẹ ọjọ Saturday. Ṣugbọn gbogbo awọn ijọ oniwasu yoku ko fi ara mọ ti ọjọ Saturday pe ọjọ na ni Ọlọrun simi, ọjọ Sunday ni ọjọ ti nwọn gbagbọ ni ti nwọn.

Eyi ni idi rẹ ti Satide si Sunday fi nṣe isin ni ọjọ Saturday, ti nwọn ko si ṣe iṣẹ kan ni ọjọ na. Awọn ijọ ti kofi ara mọ Saturday nṣe isin tiwọn ni ọjọ Sunday.

Ọjọ idibo nla ti o mbọ yi jẹ ọjọ Saturday. Iye ọmọ ijọ yi Satide - Sunday ti o mbẹ ni agbegbe Ila-orun le diẹ ni ọ k ẹ meji abọ ti nwọn ko gbọdọ na ọwọ le iṣẹ kanṣe ni ọjọ Saturday, awọn lo taku pe, nwọn ko lọ dibo ni ọjọ idibo ti mbọ nitori ti o bọ si ọjọ isinmi wọn.

Nitorina bi nwọn ko ba

WO OJU EWE KẸRIN

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ẹpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona iko, o-utu Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi j ẹ d i Kokoro osi ọmode. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsọn fọnfọn, o nmu ki ehin bibu jẹ irọ tun fun awọn ọmọde. osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamo, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko se mani fun awọn ọmode. Ijsfara lewu pupọ, tete lọ ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA
& BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street, Lagos. Phone 24247

# IMOLE

ESIN OKO WA:-
IMOLE DE OKUNKUN PARADA
Editorial Works & Office
16, Bamgbose Street, Lagos.
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street.


## Ile aiye ni abamo gbe ti ye wa

Opolopo niun Woli tOlorun ran wa si ile aiye, ohun ti nwon nfunrere ti a gbo ni wipe, eronu pawada nitori ti Ijoba Olorun ku si dede, Be na ni titi di isisiyi, igbe yi kanna ni awon Onnwasu nke.

Awon elomiran so pe lojojumo ati nigba gbogbo ni nwon nse ikilo yi lojo wo ni Ijoba Olorun na yio de, lakoko ti a wa yi, pekipeki ni Ijoba Olorun sunmo olukuluku wa. Eniti ojo iku re ba pe ni Ijoba Olorun tire deba.

Nwon ni ki a ronu piwada ki ijoba na to de. Ki eniti o njale ye ole nijija, ki apania ye pania, oniketa ye se keta, ati iru iwa buruku ba wonni. Ese ti enia ti ko sile ki ojo iku re to de, ni oluware yio jere re lorun, Ile aiye ni enia ti le se abamo, nitori abamo kosi lorun, kosi ejo kotemilorun, ko si Loya, Bi enia ko mowe nigbati o mbe nile aiye, yio ka sanda teni nigbati oluwa re ba ti wo ile.

Ronu, ki o pa iwa re da si rere, nitoripe ojo kan ko mburu fun oku bi oru ojo to koko wole sun, ko seniti koni se abamo lojona Bi o je rere ni ise re, iwo yio se abamo pe, mba mo ki nse die si. bi o ba si je ise buruku ni o se iwo yio se abamo pe, mba mo nko se nkan yi.

Ronu pa iwa da nitori Ijoba Olorun ku si dede.

## E ma ka Iwe Irohin Imole Ki e si ma polowo oja yin sinu re

## Bisimilai Rahamoni Rahim

## NIPA ISLAM

Nipa oro Michael Toye ti o so pe Aburahamu ko yan ale, mo fe ko mo daju pe teletele kise wipe awa Imale gba nkan nwonyi gbo, bikose pe a ka won si isokuso, oro rirun, irira, ati egbin lati ma ri iru won ka ninu iwe mimo ti a pe ni ti Olorun ti o fi ranse fun itosona awon omo enia. Otile je ohun ti o buru ju lati ri pe awon Woli ti Olorun ran si ar aiye lati wa to won si ona na ni Bibeli tun wa nso inu oro abuku hawonyi si.

Nitorina, bi ti Abraham ko ba da Ogbeni Toye loju, ki o wo ti Noha ti o ba awon omo bibi inu re meji sun ni Gen. 19:30-38. Jacob fe awon omo meji bibi inu iya kanna, Genesisi 29: 23-30. Jacob yan ale pelu Genesisi 30:1-10. Dafidi na yan ale meji Samuel 11: 2-27. Ammon ba omo iya re sun. Samuel. 13:1-12.

A ni Bibeli ti aye wa toni yi ko ba oro irira wonyi mo lori awon Woli Olorun nikan, bikose wipe o tun so oro rirun si Olorun eleda wa na papa.

Wo ibiti won ti so wipe Olorun ba awon enia pin ninu ikogun awon omo mundia Olorun roboto-roboto. Numeri 31:17,18,35 ati 40.

Bi Ogbeni Toye ba ka awon aye wonyi tan, yio wun mi ki o gbiyanju lati la ye mi, ona ti iru iwe olorokoro hawonyi ko fi ye lati junu tabi ki a yo awon alebu te wonyi kuro nitoripe won ti fi oro Olorun sile, won si tele tiwon Marku ori 7 ese 6 de 9, ati nitoripe won ti fi aise ododo te otito ri. Romans 1:16-19.

Emi yio ma reti esi Ogbeni Michael ni ose to nbo, mo si fi iba eyi to ni enu wo na lati mo bi o ti jinle nipa Bibeli mimo.

Akiyesi: Gbogbo awon ti won nko iwe wa ti won ko iti ri esi re ni lati se suru, bi aye tise wa nio ni ase nto ni ese se.

Kie mase kare lati ma fi iwe yin ranse si Olotu Irohin Imole.

Eo si ma ri esi re bi o ba ti kan yin.


## NJE O NI OTUTU IBA










DOKITA SO WIPE




Da OTUTU IBA re duro gbe koro "ASPRO" meji mi
ARA RE YIO SI TUN YA-GAGA

# ITUMO ALA awọn onibere

TAIRU MUKANDASI ILỌRIN—

Igbọran lẹbọ, jọwọ maṣe ba wọn lọwo ninu owo jibiti ni asiko yi, ki o ma ba lu okun ijọba, awọn ọta gbogun ti o nisisiyi, ti o ko ba ṣọra gidigidi, ẹniti o sun mọ ọ mọti-mọti ni yio jek owo te ọ, maṣe finu han ẹnikẹni.

Iwọ le bere ala tirẹ na lọwọ:—
JOSEPH ALALA
6, Ojo Road Oduabọrẹ Mushin.


# KERE O. AKIYESI PATAKI

'Awa na le jeri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS', Awa na si nlo ni ilu wa Gold Coast (Ankara) Ghana pelu, meji rẹ 'kosi ninu gbogbo orișiri-și Egbogi kakiri ilu Naijiria.




## Irohin Kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna si ni ẹwẹ ni igboro ilu Eko, irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia, ti ọmode ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi ṣe ọrọ ati oriu kọ larin ara wọn jẹ nipa ti egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni 'Leopills'

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti won ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe Bi o ti Lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JEDIJEDI bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti le pẹ to, bẹna si ni awọn tun le fi ọwọ sọ aya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuregbe, Ejẹ dudu lara, Arun Edọki, Iju, Igbẹsise tabi Aikori Igbọnsẹ dede, Inu-rirun nigbakugba, Ara-wiwo, Esanri, Ehin-didun, Oju-sisu tabi aiko riran kedere, Kokoro buruku lara, Oṣi inu, Onigbameji, ati orisirisi arun ara miran, gbogbo pẹlu 'WIPE' won yio ri alafia ni kiakia bi wọn ba nlo egbogi LEOPILLS' nitoripe asi ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata

ṢE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ
IJAFARA SI LEWU PẸLU O (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:- Igo nla Șile-mẹfa pere ni

Igo Kekere:- Șile-mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orișirisi amodi ti o ba fẹ ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8, PalmChurch Street P. O Box 333
Lagos Nigeria Phone 22878

Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE. IBADAN.

ati ni Abimbola Medicine Stores
B/9 Okesha Street Ilesha

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe sobu [illegible] n nia [illegible] ọlọmirsn [illegible] maṣe [illegible] ara.



ADVERT. NO. 160

# THREAT OF STRIKE

The following statement is issued on the authority of the Federal Government:

1. Trades Union Congress have announced that they propose to call upon their member unions, including those which represent Government staff, to come out strike from or about the 1st November, 1959, in connection with the Congress's demand for an interim award (on account of the general review of salaries and wages now proceeding)of 50% for daily paid workers and 30% for junior salaried staff, effective from 1st of February 1959.

2. The Federal Government is fully aware of the uneasiness felt by its established and unestablished employees about the present cost of living. As this matter affects officers and workers of Federal Government stationed in localities throughout Nigeria, and represented by a wide variety of unions staff associations a Commission for the review of wages and salaries has been appointed andwill shortly make recommendations to the Federal Government and those Regional Governments which are associated with it in the review. In order to alleviate existing hardships, an interim award equal to 10% of the current basic rates of salaries and wages has been granted to salaried officers on the long scales (except certain highly-paid contract employees) and to daily paid workers The purpose of the interim award is to grant interim relief, and the award is therefore effective from the 1st September, 1959, until the Commission's recommendations have been received and a decision on them is made by the Government. In view of the statistics available, and in view of the purpose for which the reviewing Commission has been appointed the Federal Government considers both the amount and the effective date of its interim award to be eminently just and reasonable.

3. The Executive body of the Trade Union Congress was informed at all stages of Government's intentions with regard to the review of salaries and wages, and their good-will was sought. The Congress was also informed that an interim award was contemplated and, since it had expressed views on this subjects, was invited to explain its views. At all stages it has been made clear to the Congress however that, because the increased cost of living is a matter which affects all workers and all the unions which represent them, neither the general wage and salary levels which will result from the review nor the amount of the interim award can be made open to negotiation. Nor, even if negotiation were possible, could the Federal Government accept the Trades Union Congress as a competent body to negotiate on behalf of Federal Government employees. In all matters properly subject to negotiation, the Federal Government will continue to act through the Whitley Councils which are the established joint negotiating bodies in respect of Civil Service conditions. The proper role of the Congress in the view of the Federal Government is that of adviser and guide to its constituent unions It should not usurp the functions which are proper to the unions themselves.

4. With regard to the Trades Union Congress's threat of strike action on or after the 1st of November, all employees of the Federal Government are reminded that to come out on strike and to attempt thus to halt or dislocate the operations of the Government is a serious breach of disciplin. Any who may contemplate going on strike, whatever kind of strike it may be, should understand clearly that—

(a) they will receive no pay while they are on strike;
(b) and They will be liable to dismissal and to the forfeiture of any pension, retiring allowance or gratuity for which they might otherwise be eligible.

# TANIMEHINOLA APA 15

Lati Owo. J. O. SHOYINKA (Mushin)

Lehin ti Esu ti fun Tanimẹhinọla ni owo tan, ti o si fi ohun alumọni aiye da ẹ̀ọla tan, o si ri pe o fi ara rẹ re dada nipa owo, biri ni o yipada lẹhin rẹ. Tanimẹhinọla kako gulutu bi a k a ni abẹ igi jegede kan, o bẹrẹsi ronu, bi o ti nronu lọwọ ni Elegbede kan yọ lokere, o nbọ habahabahaba, o rin siwaju sẹhin bi akan okun. Tararata ni o nbo wa si ọdọ Tanimẹhinọla, eru baa gidigidi, o ni ha! ha! ha! Elegbede lo nbọ yi tabi ẹranko miran? O ọra bẹrẹsi da sọ f u n ara rẹ pe ọna wo ni le gba kọlu Elegbede yi, nitoripe mo mọ ise awọn Elegbede, bi wọn ko u e a ni a ule, aluwọnidi, nwọn a fa oluware ni ika yi lẹe.

Nigbati Elegbede ku sata ki o de ọdọ rẹ, Tanimẹhinọla mura ija lati ba a ja. Sugbọn ohun ti o dẹruba Tanimẹhinọla ni pe Elegbede yi bẹrẹsi fọhun bi enia, o ni baba yi kini de o? Tanimẹhinọla ni alagba, ilu Ibẹju ni mo nlọ nitoripe wọn la mi loye pe ibi ni wọn wa. Elegbede tun bere lọwọ rẹ, o ni nje iwọ ko ha gba ilu Sokoti kọja bi? O ni bẹni, ibẹ gan ni mo ti nbọ yi Elegbede ni tẹlẹ s i l ẹ ki o gbọ, ẹnikẹni ti o ba ti ba Sokoti ati Esu Ọdara da nkan pọ, ko le re ilu yi kọja si ilu Ibẹju, ayafi ti o ba jewọ ẹṣẹ, nitoripe ilu ti o wa lọkan ni, "JẸWỌ ẸṢẸ" ni.

Tanimẹhinọla ni Baba mi Elegbede jọwọ fi o n a han mi, iba enyin agbalagba o. Elegbede ni ma jafara, dide logan ki o maa lọ ni ọkan ni, afara meji ti wọn tẹle ori Odo n l a ti iwọ yio re kọja, afa ti o ulo jọbọjọbọ ni ki o gun kọja, maṣe g u n eyiti o nipọn pongbara yen, nitoripe iri ti o ba ri, ọkan rẹ yio bale pe afara na lagbara, ti o ba gun penren, ogbun iparun ni iwọ yio jasi o, sugbọn ti o ba gun ekeji kọja, alafia ni iwọ yio re ọja, ti o ba fẹ ki o se gẹgẹbi mo ti wi fun ọ, aikọsẹbẹ, abamọ ni yio jasi fun ọ.

Tanimẹhinọla nlọ sasasa, nigbati o de eti bebe odo yi, loto afara meji ni wọn tẹle ọdọ yi lori, o rerin musẹn, o ni ha! ... ṣe a tan ni fun ọfin ni Elegbede yi o bi oju mi tilẹ fọ, ti iye mi si ra bamubamu mo ha le foju ara mi silẹ ki nlọ gori afa ti ko lẹmi. Elegbede yi tilẹ to pe on ti ri Dani Ọlọra senkẹnsenkẹn niyen? Ori gada ti nipọn ni ngo gba o.

Akiyesi:— Lọsẹ to nbọ, ẹ o ma ka apa 46, nipa bi o ti se gun ori afa na, ati ohun ti o sẹlẹ si, mo ki gbogbo enyin Onkawe mi ẹ ku ipalẹmọ Ọ d u n Keresimesi, Oluwa yio jẹki o sojú emi o. Ase.

# Otelemuyen nki nyin o

Ọtẹlẹmuyen nki nyin o, ọdun ọdun ni a s'oju nyin peregede la o ye o. A s e, gbogbo ọrọ mi di ọsẹ to nbọ lagbara Odua, dori ko deri, o doro awọn ỌMỌ YAGO F'SU ni ọjọ Xmas ati ọsẹ to nbọ ni mo ti fẹ ma kigbe wọn nitori jagadijagan wọn ki ọwọ ọlọpa ba le tẹ wọn ni rọwọ rọsẹ ninu ọdun yi.

Ẹyin IPANLE ọ m ọ ẹ mura de mi o -Otẹlẹmuyẹn

## LATI OJU EWE KINI

yẹ ọjọ idibo na kuro ni ọjọ 12th oṣu December 1959 si ọjọ Friday 11th gbogbo ọmọ ẹgbẹ Satide-Sunday bi iwọn ọke meji pẹlu abọ enia, ko ni ba wọn lọwọ sinu ibo didi.

Ọgbẹni A. J Dike ti o jẹ baba ẹgbẹ ijọ na sọ wipe awọn ko ni gba ẹni kan ninu ọmọ ẹgbẹ wọn l a y e lati lọ dibo ni ọjọ isimi wọn ati wipe on ti ranṣẹ

Eyi nikan kan, Ọgbẹni Dike sọ wipe Ranti ọ j ọ Isimi lati lo o ni mimọ, ni fifinna, awọn ko ni gba fun ẹnikẹni lati fi ile Isin wọn ṣe ile idibo lọjọ na.

## Gongo so ni Idumota

Gọngọ sọ! irohin ko to afojuba lọjọ ọsẹ ana, wọmi na ẹnikeji! ẹniti kol rin ni ki agbe on. Awọn ẹniti ko ri iran na wo, h l iran tirẹ din kan. Bi o ba nwo awọn Sọja ti nwọn nrin, tinwọn nyan, ti nwọn si njo pẹlu, gba fi seranwo ni iran na jẹ.

Bi otilẹ jẹ wipe iran na ko ku ku nse ohun itun sibẹ awọn ti kori iran ti ana yi wo, iran wiwo wọn ko se alaidin kan.

Iran na bẹrẹ lati ebute Ehingbẹti ninu Sọsi Alagogo a ti de ibẹ ki agogo mẹwa awurọ to lu E g b ẹ awọn Ologun, ti Olọpa, ti awọn Ologun oju omi(Sailors) tsẹ awọn Olotu Ijọba gbogbo lo ti peju p e s ẹ sinu ile Isin, Gomina agba wanibẹ, Prime Miniser wa awọn Minister ti joko nipo wọn atawọn ọmẹgbẹNEWA

# H M N S NIGERIA



Ọkọ ogun ti a nwo yi ni (Destroyer) ti awọn Gẹsi kan fun ọmọ ogun oju omi tilẹ Najiria o sẹ jẹ gunlẹ si Eko ni ọjọ Saturday 7th osu November 1959. Lati ilu Oyinbo nigbati o mbọ, o ya ni ilu Gibralter, Bathurst, ati Free Town. Nigbati o ba de ... ọjọ Sunday ati Monday 8th ati 9th osu November ni akoko ... ye wa fun g b o g b o en a ... lọ yẹ ọkọ na wo.

Ọgagun ti jọ lo mbẹ ninu ọkọ ogun na. awọn mẹji ninu wọn jẹ ara ilẹ Najiria awọn Sailor yoku jẹ adọrun enia gbogbo jẹ ara ilẹ Najiria.

Agbọ wipe ẹrọ ti o nsiṣẹ ninu rẹ lagbara to ti ẹgbaa ẹsin(2000 Horses Power) lati Eko si ilu Oyinbo jẹ ẹgbaji (4000) buso. B... ọkọ yi ba fi gbo... gbo agbara rẹ ... ẹ sere tan, bi ... ba kuro ni Eko, yio gunlẹ ilu Oyinbo ni ọjọ kẹrin.

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Olotu E. A ADENIJI 51, Tejuosho Street, Suru-lere, YABA.